**ÀKÓJỌPỌ̀ ÀBÁJÁDE ILÉ-IṢẸ́ AYẸ̀WÉ-OWÓ-WÒ ÀGBÀ LÓRÍ ÈTÒ ÌṢÚNÁ ÌJỌBA ÌPÍNLẸ̀ ÈKÌTÌ FÚN ỌDÚN 2021.**

## 1.0 ÀMÚLÒ ÈTÒ ÌṢÚNÁ

- Ètò ìṣúná ọdún 2021 jẹ́ ètò ìṣúná èyí tí owó tó wọlé àti owó-iná yóò jẹ́ dọ́gba-n-dọ́gba iye owó tí a lérò pé yóò lé ní Bílíọ̀nù Ọgọ́rùn-ún lé mẹ́sàn-án Náìrá (₦109,666,376,722.68).

- Owó tó wọlé ní ọdún náà lé ní Bílíọ̀nù méjìléláàádọ́fà àbọ̀ Náìrá (₦112,786,631,247.98) nígbà tí owó ìná le ní Ḿílíọ̀nù mẹ́rin lé lọ́gọ́rùn-ún Náìrá (₦104,435,363,456.00) tó túmọ̀ sí pé owó tó wọlé lé ní ìdá ọgọ́rùn-ún lé méjì (102.85%) nígbà tí owó iná lé ní ìdá márùn-ún lé láàádọ́rùn-ún nínú ìdá ọgọ́rùn-ún (95.23%)

- Owó tí iye rẹ̀ le ní Bílíọ̀nù mọ́kàn lé láàádọ́rin Náìrá (₦71,288,328,537.98) tó jẹ́ owó tó wọlé látìgbàdegbà nínú ètò owó ìṣúná tí iyé rẹ̀ dín ní Bílíọ̀nù márùn-ún lé lọ́gọ́ta Náìrá (₦ 64,923,714,770.55) tó lé ní ìdá ọgọ́rùn-ún lé mẹ́sàn-án (109.80%) èyí tó kéré níye ju ìdá tó lé ní àádóje dín mẹ́rin (126.39%) ti ọdún tó kọjá.

- Ọ́pọ̀ nínú owó àtìgbàdégbà ló wọlé láti inú àṣùwọ̀n Ìjọba Àpapọ̀ tó lé ní Bílíọ̀nù mẹ́ta lé láàádọ́tá àbọ̀ Náìrá (₦53,720,548,410.00) tó dín díẹ̀ ní ìdá mẹ́rin dín lọ́gọ́ta (55.96%) nínú ọgọ́rùn-un iye owó tó wọlé lọ́dún tó kọjá

- Owó tó wọlé sápò Ìjọba Ìpínlẹ̀ ní ọdún 2020 tó lé ní ọgbọ̀n Bílíọ̀nù Náírà (₦30,307,574,587.81) kéré níye sí ti ọdún 2021 tó lé ní Bílíọ̀nù mọ́kànlélọ́gbọ̀n àbọ̀ Náírà (₦ 31,661,430,473.00) ní ìdá tó lé mẹ́rin (4.47%). Owó tó wọlé lápapọ̀ sápò Ìjọba láti ọ̀dọ̀ Ìjọba Àpapọ̀ ni odun ti a n gbe yewo lé ní Bílíọ̀nù mẹ́tàléláàádọ́ta àbọ̀ Náírà (₦53,720,548,410.00) èyí tó gbé pẹ́ẹ̀lì jú ti ọdún 2020 tó lé díè ní Bílíọ̀nù mọ́kàndínláàádọ́ta Náìrá (₦49,054,753,547.99) tí iye tó fi gbé pẹ́ẹ̀lí si dín ní Bílíọ̀nù márùn-ún (₦4,665,794,826.01) tó jẹ́ ìdá mẹ́sàn-án àbọ̀ nínú ìdá ọgọ́rùn-ún (9.5%).

- Owó tó wọlé lábẹ́lẹ̀ lọ́dún 2020 tó lé ní Bílíọ̀nù mẹ́wàá àbọ̀ Náírà (₦10,557,553,945.05) kéré níye sí iye owo tó wọlé ní ọdún 2021 tó lé ní Bílíọ̀nù mẹ́tàlá àbọ̀ Náírà (₦13,620,433,129.00) èyí tó fi gbé pẹ́ẹ̀lí si jẹ́ ìdá mọ́kànlélọ́gbọ̀n lé díè (29.01%) nínú

ìdá ọgọ́rùn-ún. Èyí tí iye tó fi gbé pẹ́ẹ̀lí si dín ní Mílíọ̀nù Ọ̀ọ́dúnrún lé méjìléláàádọ́ta sí Bílíọ̀nù Mẹ́rin dín díè Náìrá (₦ 351,747,963.39 si ₦ 3,947,347,001.00) tó jẹ́ ìdá ẹgbẹ̀rún lé méjìlélógún àti ìpín mọ́kànlélógún (1,022.21%) nínú ìdá ọgọ́rùn-ún.

- Owó tó wọlé láti òkèèrè jẹ́ owóyàá tó wọlé láti òkèèrè lọ́dún nàà ju ti ọdún tó kọjá (2020) láti owó tó lé ní Bílíọ̀nù mẹ́rin àbò Náírà (₦4,602,418,947.76) sí owó tó lé ní Bílíọ̀nù márùn-ún àbò Náírà (₦5,765,039,628.00). Owóyàá lábẹ́lẹ̀ ga sókè si i láti iye owó tó lé ní Bílíọ̀nù mẹ́sàn-án àbò Náírà (₦9,629,669,867.43) sí iye owó tó lé ní Bílíọ̀nù Méjìlá àbọ̀ Náírà (₦12,760,622,179.00) ní ọdún 2020. (Owóyàá láti Bánkì àti Ètò Ìlànà ẹ̀yáwó fún isẹ́ àgbẹ̀ (Commercial Bank Loans and Commercial Agric Credit Scheme, CBN Scheme, CBN COVID Health Intervention), ní ọdún 2021

- Iye Owó tó wọlé pàtó lé ní Bílíọ̀nù mẹ́rìnlelogun àbọ̀ Náìrá (₦24,716,388,620.00) èyí tó yàtọ̀ sí iye owó tó dín díè ní Bílíọ̀nù Métàlélọ́gbọ̀n Náìrá (₦32,906,761,952.13) tí a lérò pé yóò wọlé. Èyí tó já sí ìdá márùn-ún lélọ́gọ́rin lé dìẹ̀ (75.11%) nínú ìdá ọgọ́rùn-ún èyí tó lọ sókè sí i ní ìdá ogún lé kan (20.1%) tí a bá fí wé ìdá márùn-ún léláàádọ́ta ó lé díẹ̀ (55.01%) tí ọdún tó kọjá

- Owó-iná fún ọdún 2021, dín ní Bílíọ̀nù mẹ́rìnlelọ́gọ́ta Náìrá (₦63,953,776,060) tó din ní ìdá ọ́gọ̀rún-ún (99.98%) nínú ọgọ́rùn-ún nínú ìṣàmúlò ètò ìṣúná. A ṣe àkíyèsí pé owó iná àtìgbàdégbà lé ní ìdá mérindínláàádọ́rin (66.61%) iye àpapọ̀ owó tó wọlé àti àpapọ̀ iye tó dín ní ìdá àádọ́rùn-ún (89.71%) owó tó wọlé, látìgbàdégbà ní ọdún ti à ń gbé yẹ̀wò.

- Iye owó tó jẹ́ owó-iná fún ọdún nàà lé ní ogójì Bílíọ̀nù Náírà (₦40,481,587,406.00) èyí tó lé ní ìdá méjì dín láàádọ́rùn-ún (88.58%) ìṣàmúlò ètò ìsúná, tó lé ní ìdá meji le logoji (42.16%) àpapọ̀ owó tó wọlé fún ọdún nàà. Ìdá mẹ́ta lé lọ́gọ́jọ (163.78%) àpapọ̀ owó tó wọlé àti ìdá tó dín ní ìdá mọ́kàndínlógójì (38.76%) ní iye owó ìná pàtó fún ọdún náà. Ní ọdún tí à ń gbé yẹ̀wò, àpapọ̀ owó tí a lérò pé a ó nà-án sí iye tí a ná jẹ́ ìwọ̀n 1:1.4, nígbà tí ìwọ̀n tí a se àkọọ́lẹ̀ jẹ́ 1:1.6. Àbájáde wa ni pé ètò ìsúná ti ọdún nàà dára ju ti ọdún tó kọjá

- Ilé Iṣẹ́ Ayẹ̀wé owó-wò ṣe àkíyèsí pé ètò ìṣúná ti ọdún 2021 kò kúnjú ìwọ̀n tó torí pé àpapọ̀ owó tó wọlé dín ní Bílíọ̀nù Mẹ́tàlélọ́gbọ̀n Náírà (₦32,906,761,552.13) nígbà tí owó-iná lé ní Bílíọ̀nù Márùn-ún dínláàádọ́ta Náírà (₦45,697,073,657.67). Ẽyí túmọ̀ sí pé iye owó tó dín ní Bị́ḷíọ̀nù mẹ́tàlá Náírà (₦12,790,311,705.54) ni wọ́n gbérò láti ná nínú ètò ìsúná nàà ṣùgbọ́n tí wọ́n ko yà owó sọ́tọ̀ fún. Ètò ìṣúná jẹ́ ohun èlò ètò ìṣètò tí a gbọ́dọ̀ ṣe láíkùnà

2.00 **ÀKÍYÈSÍ ÀTI ÀBÁ ILÉ-IṢẸ́ AYẸ̀WÉ-OWÓ-WÒ ÀGBÀ LÓRÍ ÌṢÀMÚLÒ ÈTÒ ÌṢÚNÁ.**

- Ó dà bí eni pé iye owó tí a fọkàn sí pé yóò wọlè nínú ètò ìṣúná ti pọ̀jù tí èyí sì mú kí àlàkalẹ̀ ètò ìṣúná má wá sí ìmúṣẹ èyí tí a ti tọ́kà sí tẹ́lẹ̀ rí ni wọ́n ti ṣàtúnṣe rẹ̀ nínú ètò ìṣúná tí ọdún tí a ń gbé yẹ̀wò yìí.

- Iye owó-iná tí SFTAS ti se àlàkalẹ̀ sí < ìdá márùndínlọ́gbọ̀n, ìdá ogún, àti ìdá márùn -–ún dínlógún <25% < 20% àti <15% ní ṣíṣẹ̀-ǹ-tẹ̀lẹ́ fún ọdún 2019, 2020, 2021 ní ṣíṣẹ̀-ntẹ̀lé. Iye owó-ìná wá já sí ìdá mẹ́rin lé díẹ̀ (4.76%) tí ti ọdún yìí wá já sí ìdá márùn-ún dínlógún (15%) tí ọdún nàà.

- Ó ṣe pàtàkì láti wá àwọn ọ̀nà mííràn tí owó yóò fi máá wọlé kí owó tó-ń-wọlé sápò Íjọba lè búrẹ́kẹ́ si i

- Kí Ìjọba Ìpínlẹ̀ ṣe àfihàn àti ìpolongo àwọn ohun àmúṣọrọ̀-ajé Ìpímlẹ̀ yíí fún àgbáyé rí nípa ṣíṣètò ìpàdé àpérò àti ìlanilọ́yẹ lórí ètò ọrọ̀-ajé láti fa ìfẹ́ àwọn olùdáṣẹ́-sílẹ̀ lábẹ́lẹ̀ àti lókè òkun wá sí Ìpínlẹ̀ yíí

3.00 **OWÓ TÓ WỌLÉ LÁBẸ́LÉ.**

- Owó tó wọlé lábẹ́lẹ̀ lọ́dún náà lé ní Bílíọ̀nù Mẹ́tàlá àbọ̀ Náìrá (₦13,620,433,129.00) èyí tó fi iye tó lé ní Bílíọ̀nù Mẹ́ta Náírá (₦3,062,879,183.95) gbé pẹ́ẹ̀lí ju ti ọdún 2020 tó lé ní

Bílíọ̀nù Mẹ́wàá àbọ̀ Náìrá (₦10,557,553,945.05). A ṣe àkíyèsí pé owó tó wọlé lábẹ̀lẹ́ lọ́dún tí a ń gbé yẹ̀wò búrẹ́kẹ sì ju ti ọdún tó kọjá lọ tó kéré níye tí a bá fi wé ti àwọn ọdún 2015, 2016, 2017, 2018 àti 2019 ní ṣíṣẹ̀-ntẹ̀lẹ́ (₦1,064,417,745.00, ₦1,077,460,735.13, ₦2,432,771,819.54, ₦47,300,813.35 àti ₦3,425,563,015.93). Èyí ṣàfihàn ìdàgbàsókè tó bá owó tó wọlé lábẹ̀lé àti pé ọ̀rọ̀ kòró (COVID-19) kó nípa mọ̀ lórí owó tó ń wọlé lábẹ̀lé.

- Bí àbájàde yíí kò ti wúni lórí síbẹ̀ ìṣàmúlò ètò ìṣúná gbé pẹ́ẹ̀lí si i láti ìdá ọgọ́rùn-ún lé mẹ́rin (104%) ní ọdún 2020 sí ìdá tó dín méjì lé láàádọ́rin (91.81%) ní ọdún 2021 èyí ṣàfihàn ètò ìṣúná abẹ̀lé tí kò lágbára tó. Owó tó wọlé lábẹ̀lẹ́ gbé pẹ́ẹ̀lí sí àpapọ̀ owó tó wọlé ní ìdá tó lé díè ní ìdá méjìlá (12.14%) sí ìdá tó lé ní Mẹ́rìnlá (14.19%) ti ọdún yìí.

- Owó tó wọlé lábẹ̀lẹ́ láìse owó orí láti àwon Ilé-iṣẹ́ Ìjọba (MDA's, Parastal and Tertiary Institution) àti Ilé-Ẹ̀kọ Gíga le ní Bílíọ̀nù mefa Náírà (₦6,333,439,408.00) tí ìṣàmúlò ètò ìṣúná rẹ lé ní ìdá mẹ́ta dín láàádọ́rùn-ún (87.22%) Iye owó yìí dín níye púpọ̀ tí ìyàtọ̀ rẹ̀ le ní Bílíọ̀nù Méjì Náìrá (₦2,371,930,244.00) tó jẹ́ ìdá tó dín ní ọgọ́ta (59.87%) tí a bá fi wé ti ọdún 2020 tó dín ní Bílíọ̀nù mẹ́rin Náírà (₦3,961,509,164.00)
- Owó ìdókòwò tí a ń retí pé kó jẹ́ Ẹgbẹ̀rún lọ́nà ogún Náìrá (₦ 20,000) ni owó tó wọlé níbẹ̀ jẹ́ Ẹgbẹ̀rún Márùn-ún dín lógún Náìrá (₦ 15,000). Eléyìí jẹ́ kàyéfì fún àwọn ayẹ̀wé-owó wò gẹ́gẹ́ bí ó ti jẹyọ nínú àbájáde ti ọdún tó kọjá. Láti máa retí owó tí iye rẹ̀ jẹ́ ogún ẹgbẹ̀rún Náìrá (₦ 20,000) gẹ́gẹ́ bí ó ti jẹyọ nínú ètò ìṣúná lórí ìdókòwò tí iye rẹ̀ lé ní Bílíọ̀nù méjìlá Náìrá (₦12,227,877,500.00) kò bójúmu, ósì jẹ́ àlàkalè tí kò péye owó tí a lérò pé yóò wọlé nídìí ìdókòwò.

- Ó yẹ kí wọ́n ṣe àgbékalẹ̀ Igbìmọ̀ Apowó- wọlé láti ṣe ìjíròrò pẹ̀lú Ilé-iṣẹ́ Ìjọba **(MDAS)** láti ṣe àlàkalẹ̀ ọ̀nà bí owó yóò ṣe máà wọlé. Ìwé akọ̀ọ́lẹ̀ olóṣooṣù lórí bí wọ́n ṣe pawó wọlé láti Ilé- iṣẹ́ Ìjọba ni wọ́n gbọ́dọ̀ máá mú ṣọwọ́ sí Ìgbìmọ̀ Apowó- wọlé nàà kí wọn sí ṣàlàyé ìdí tí owó kò fi wọlé nígbà tí owó kò bá wọlé. Ìgbìmọ̀ náà sí gbọdọ̀ tètè wá ojútùú sí àwọn ìṣòro tí Ilé-iṣẹ́ Ìjọba bá n kọjú.

- Àròpọ̀ gbogbo owó-orí tó wọlé lọ́dún nàà lé ní Bílíọ̀nù Méje Náírà (₦7,286,993,719.00) nínú èyí tí owó tó dín díẹ̀ ní Bílíọ̀nù Mẹ́fa Náírà (₦5,880,018,522.00) tó lé ní ìdá ọgọ́rin (80.69%) jẹ́ owó-orí tó wọlé láti ọ̀dọ̀ àwọn òṣìṣẹ́ Ìjọba (PAYE)

- Owó-orí tó wọlé láti ọ̀dọ̀ àwọn tí kìí ṣe òṣìṣẹ́ ìjọba àti owó ìdàgbàsókè nínú àpapọ̀ owó tó wọlé lábẹ́lẹ̀ jẹ́ ìdá méjì dín díẹ̀ (1.99%) àti ìdá méjì lé díẹ̀ (2.27%) ní ọdún tí à ń gbé yẹ̀wọ̀. Owó-Orí àwọn tí kì í ṣe òṣìṣẹ́ ìjọba dínkù sí iye tó wọlé lọ́dún tó kọjá tó dín ní ìdá márùn-ún àbọ̀ nínú ọgọ́rùn-ún (5.48%) nígbà tí owó ìdàgbàsókè gbé pẹ́ẹ̀lí si ju ti ọdún tó kọjá níye tó lé ní ìdá kan (1.06%) tí a bá fi wé àpapọ̀ owó tó wọlé lábẹ́lẹ̀.

- Gbígba owó-orí wọlé láti ọ̀dọ̀ àwọn tí kì í ṣe òṣìṣẹ́ Ìjọba jẹ́ ọ̀nà láti mú kí owó-orí gbé pẹ́ẹ̀lì sí i. Nípa báyìí, a gba Àjọ tó ń gbowó wọlé lábẹ́lé (SIRS) nímọ̀ràn láti jára mọ́ṣé láti ri i pé àwọn tí kì í ṣe òṣìṣẹ́ Ìjọba san owó-orí wọn

## 4.00 FÍFÚN ÀWỌN ILÉ-ISẸ̀ ÌJỌBA NÍ OWÓ-ÌNÁ.

- A se àkíyèsí pé owó-afísisẹ́ àkànse àti owó-iná tó yẹ fún Ilé-iṣẹ́ ni kò tẹ̀ wọ́n lọ́wọ́ gẹ́gẹ́ bí àgbékalẹ inú ètò ìṣúná. Àwọn Ilé-iṣẹ́ tí a ti ṣe àlàkalẹ̀ owó bí iye tó lé ní Bílíọ̀nù Mẹ́rin Náìrà (₦4,048,212,348.66) fún ni kò rí owó kankan gbà ní ọdún nàà nígbà tí àwọn Ilé-iṣẹ́ Ìjọba (**MDAS)** tó ye kó gba iye owó-tó dín díẹ̀ ní Mílíọ̀nù irinwo din mewaa Náírà (₦389,697,286.82) kò rí gbà ju owó tó lé ní Mílíọ̀nù Mẹ́tàdínlọ́gọ́rin Náírà (₦77,107,500.00) tó jé ìdá ogún dín díẹ̀ (19.79%) nínú ìdá ọgọ́rùn-ún.

## 5.00 OWÓ-ÀNÁJÙ ÀWỌN ILÉ-IṢẸ́ ÌJỌBA

- A ṣe àkíyèsí pé àwọn Ilé-isẹ̀ Ìjọba bí i mẹ́tàlélọ́gbọ̀n (33) ni wọ́n ná ànájù owó tí iye rẹ̀ lé ní Bílíọ̀nù méjì àbọ̀ Náírà (₦2,680,550,622.21) ní ọdún tí à ń gbé yẹ́wò. Ìyàtọ̀ èyí tí iye rẹ̀ lé kenkà tó lé ní Bílíọ̀nù méjì àbọ̀ Náìrá (₦2,630,311,496.37) àti iye tó dín díẹ̀ ní Bílíọ̀nù méjì àbọ̀ Náìrá (₦2,469,509,888.14) tí a bá fiwé iye tó lé ní àádọ́ta Mílíọ̀nù Náìrá (₦50,239,165.84) àti iye tó lé ní igbalémọ́kànlá Mílíọ̀nù Náìrá (₦211,040,774.07) ti ọdún 2019 àti 2020 ní ṣíṣẹ̀-n-tẹ̀lé.

- Iye owó tó lé ní Mílíọ̀nù Ọ̀ọ́dúnrún lé mẹ́rìnlélọ́gbọ̀n àbọ̀ Náírà (₦334,596,469.00) tó jẹ́ ànálé owó ìfẹ̀yìntì àti iye tó dín díè ní irínwó lé mọ́kànlá Náírà (₦410,911,865.00) ni ó jẹ́ ànálé owó ìsimi (pension) lẹ́yìn iṣẹ́.Gbogbo owó ìfẹ̀yìntì tó yẹ kí wón san fún ọdún nàà yàtọ̀ sí èyí tí wọ́n san ni wọ́n sọ di owó-iná gẹ́gẹ́ bí àlákalẹ̀ (**IPSAS)** nípa báyìí, ó yẹ kí wọ́n ṣe àlákalẹ̀ ètò ìṣúná tí yóó kúnjú ìwọ̀n gẹ́gẹ́ bí Ilé-iṣẹ́ Ayẹ̀wé-owó-wò ti ṣàtenumọ́ rẹ̀ nínú ìwé àkọọlẹ́ rẹ̀ ti tẹ̀lẹ̀. Àwọn òṣìṣẹ́ tó ń ṣètò ìṣúná owó gbọ́dọ̀ ṣe àkíyèsí yìí tí wọ́n bá ń ṣàkọsílè ètò ìṣúná lọ́jọ́ iwájú.
- Àlàkalè ìsòrí owó fún ọdún náà fihàn pé ilé-iṣé ìjọba (MDAs) mẹ́jo ní ànálé owó-ìná tí iye rè lé ní Mílíọ̀nù ọ́gọ́rùn-ún lé mẹ́fà àbọ̀ Nàírá (₦106,690,596.87) tí a bá fi wé iye owó-ìná tó yẹ kí wọ́n ná lọ́dún náà tó lé ní Mílíọ̀nù Ọ̀ọ́dúnrún àti márùn-ún dín láàádọ́ta Náìrá (₦ 345,188,222.41) Eléyìí pọ̀ níye sí i ní iye tó dín ní Mílíọ̀nù Mẹ́tàdínláàdọ́rin Náìrá (₦66,658,633.37) tí a bá fi wé ànálé tọdún tó kọjá tí iye rè lé díè ní Ogójì Mílíọ̀nù Náìrá (₦40,031,963.50).

- Iye owó àbùmọ́ tí iye rẹ̀ dín ní Ọ̀tàlélẹ́gbẹ̀ta Mílíọ̀nù Náírà (₦659,124,479.20) ní àwọn Ilé-isẹ́ Ìjọba kan àti Ilé-Èkọ́ Gíga ni ó wáyé nípa àṣìṣe aise àrópọ̀ owó tó wọlé lábẹ́lé fún ilé-Èkọ́ Gìga àti owó tí Ìjọba yà sọ́tọ̀ fún wọn nínú ètò ìṣúná. Àwọn Ilé-iṣẹ́ tó ń ṣétò ìṣúná kò ṣe àtúnṣe àṣìṣe yìí gẹ́gẹ́ bí Ilé-iṣẹ́-Ayẹ̀wò-owó-wò ti tọ́ka sí í nínú àkọ́ọ́lé ti ọdún tó kọjá lọ
- Owó ànálé tí iye rẹ̀ lé ní Bílíọ̀nù Kan Náìrá (₦ 1,278,121,922.17) ni a ṣàkíyèsí pé ilé-iṣé ìjọba mẹ́fà (MDAs) ná ní ọdún tí à ń gbé yẹ̀wọ̀. Eléyìí pọ̀ níye ju ti ọdún tó kọjá lọ ní iye owó tó lé ní Mílíọ̀nù Irínwó lé ọ́kànléláàdọ́rin Náírà (₦471,263,812.16). Ó ye kí ilé-iṣé ètò ìṣúná àti ìdàgbàsókè ọrọ̀-ajé ṣe ọ̀rínkíníwín àmójútó fún àlàkalẹ̀ ìnáwó láti máṣe sí ànálé tàbí ànájù.

## 6.00 ÁWỌN OHUN ÌNÍ ÀTI GBÈSÈ

- Kò sí àjẹṣẹ́kù owó àkopamọ́ tí a ṣe àkíyèsí lópin ètò ìṣúná ọdún nàà nígbà tí àpapọ̀ owó tó ṣẹ́kù sí Báǹkì títí di ọjọ́ kọkànlélọ́gbọ̀n oṣù kéjìlá ọdún 2021 lé ní Bílíọ̀nù mẹ́jọ Nàìrá (₦8,351,267,791.48)

- Ó ṣe Pàtàkì kí ètò tó múná dóko wà nípa ètò ìnáwó kí owó tó pọ̀ má kàn má wà lọ́wọ́ tàbí ní Báńkì. Èyí máá jẹ́ kí a pàdánù owó tó yẹ kó wọlé lórí owó bẹ̀ẹ̀ láìfi dókówò. A gbọ́dọ̀ ṣàkíyèsí bí àkókò àti bí owó Náírà ṣe ń lọ sókè-sódọ̀ lágbáàyè

- Owóyáà Ìjọba Ìpínlẹ̀ títí di ọjọ́ kọkànlélọ́gbọ̀n oṣù kejìlá ọdún 2021 (31st Dec, 2021) jẹ́ iye owó tó dín díẹ̀ ní Bílíọ̀nù mọ́kàndínlọ́gọ́rin Náírà (₦78,801,371,523.00) gẹ́gẹ́ bí owóyáà látòkèèrè nígbà tí iye tó lé ní Bílíọ̀nù mejidinlááàdọ́ta Náírà (₦48,108,129,669.00) bí owóyàá lábẹ́lẹ̀ tí àropọ̀ rẹ̀ dín díẹ̀ ní Bílíọ̀nù Mẹ́tàdínlááàdóje Náírà (₦ 126,909,501,193.00)

- Àwọn gbèsè míìràn tí Ìjọba Ìpínlẹ̀ jẹ títí ti ọjọ́ kọkànlélọ́gbọ̀n oṣù kejìlá ọdún 2021 ni iye rẹ̀ le díẹ̀ ní Bílíọ̀nù Mọ́kàndínlọ́gbọ̀n Náírà (₦29,290,912,700.00). Tí a bá se àropọ̀ gbogbo gbèsè tí Ìjọba Ìpínlẹ̀ jẹ, iye rẹ̀ lé díẹ̀ ní Bílíọ̀nù Mẹ́rìndínlọ́gọ́jọ Náírà (₦156,200,413,893.00).

- Àropọ̀ owóyáà (lókééré, àti lábẹ́lé) tó wọlé fún Ìjọba Ìpínlè lọ́dún náà lé ní Bílíọ̀nù Méjìdínlógún àbọ̀ Náírà (₦18,525,701,807.00) nígbà tí owóyáá tí Ìjọba Ìpínlẹ̀ san padà lé ní Bílíọ̀nù mẹ́sàn-án àbọ̀ Náírà (₦9,505,679,946.93) èyí tó jé Mílíọ̀nù mẹ́rin Náìrá lé díẹ̀ (₦4,150,759,013.09) jẹ́ àsanpadà ojú owó owóyáá tí èlé rẹ sí lé ní Bílíọ̀nù Márùn-ún Náírà (₦5,354,920,933.84) ní ọdún 2021.

- Àkíyèsí Ilé-iṣẹ́ Ayẹ̀wé-owó-wò ní pé ní ọdún nàà gbèsè sí owó tó wọlé sí Ìpínlẹ̀ le ni ìdá méjì lé logota (162.70%) títí di ọjọ́ kọkànlélọ́gbọ̀n oṣù kejìlá ọdún 2021 Élèyí pọ̀ níye ju ti ọdún 2020 ní ìdá ogún àti ìpín àádọ́rin (20.70%) èyí tó jẹ́ ìdá ogóje lé méjì (142%).

- Èrò Ilé-iṣẹ́ Ayẹ̀wé-owó-wò ní pé tí Ìjọba Ìpínlẹ̀ bá n tẹ̀síwájú láti máá gbẹ́kẹ̀lé ẹ̀yáwó fún ṣíṣètò ìnáwó fún ohun èlò rẹ, gbèsè Ìjọba yóò kọjá àfaradà ní kòpẹ́-kò- jìnà

- Nípa báyìí Ìjọba nílò láti ṣe ìró lágbára fún àwọn ohun èlo rẹ̀ nípa níní àjọṣepọ̀ pẹ̀lú àwon Àjọ Aládàáni àti Ọlọ́danni láwùjọ

## 6.00 ṢÍṢE ÀMÚLÒ ÈTÒ ÌNÁWÓ TI IPSAS

- `Igbésẹ̀ tó làmìlaka ni Ìjọba tí gbé nípa ṣiṣé àmúlò ètò ìnáwó tí **(IPSAS)** nípa gbígba Olùwádìí láti ṣe àgbéndè rẹ

- Ṣíṣe ìgbélé òṣùwòn fún ohun ìní tó ṣe kókó nínú ṣíṣe ètò náà ní kò jẹyọ nínú gbígbé iṣẹ́ fún agbaṣẹ́-ṣe

- Kò sí iṣẹ́ tí wọ́n fún Ayẹ̀wé-owó-wò nínú àgbékalẹ̀ náà. Wọ́n gbọ́dọ̀ fàyè gba àwọn ayẹ̀wó-owó-wò nínú àgbékalẹ̀ náà kí wọ́n lè máà ṣe àyẹ̀wò gbogbo àbájàde ètò náà.

- Àwọn akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ bí àwọn wọnlẹ̀-wọnlẹ̀ adíye lé dúkìá àti àwọn míìràn ní wọ́n gbọ́dò kópa nínú ìdíye lé ohun ìní láti mú àdínkù bá owó tí yóò ná Ìjọba

## 8.00 ÀÌSÍ ÀWỌN ÌSỌ̀RÍ TÓ FÚN ÈTÒ ÌNÁWÓ NÍNÚ ÈTÒ ÌṢÚNÁ

- Ànájù owó ìfẹ̀yìntì tí iye rẹ̀ jẹ́ owó tó dín díẹ̀ ní Ọ̀rìnlé lẹ́ẹ̀dẹ́gbẹ̀rin lé mẹ́ta Mílíọ̀nu (₦782,760,544.41) Bílíọ̀nù kan àbọ̀ le díẹ̀ (₦1,765,021,112.11) àti Bílíọ̀nù kan àbọ̀ din díẹ̀ (₦1,459,386,654.86) Náírà ati iye tó lé ní Bílíọ̀nù méjì àbọ̀ Náírà (₦2,637,099,209.88) fún àwọn ọdún 2017, 2018, 2019, 2020 ní ṣíṣẹ̀-n-tẹ̀lé. Èyí jẹ́ àyọrísí aìpèsè owó lọ́pọ̀ tó nínú ètò ìṣúná
- Ó ṣe pàtàkì kí ìpèsè owó tó tó wà fún owó ìfẹ̀yìntì àti owó ìsimi lẹ̀nu iṣẹ̀ oṣooṣù tó yẹ ní sísan fún ọdún kan laì kí ì ṣe èyí tí **(IPSAS)** ṣe àgbékalẹ̀ rẹ. Ìpèsè owò náà yẹ kó wà nínú ètò ìṣúná ní ìbámu pẹ̀lú àlàkalẹ̀ tí **(PTAD)** bá gbé kalẹ̀

## 9.00 OWÓ-INÁ TÍ KÒ SÍ NÍNÚ ÈTÒ ÌṢÚNÁ

- Ilé-iṣẹ́ Ayẹ̀wò owó wò ṣe àkíyèsí pé owó tí wọ́n gbà lára owó iṣẹ́ àkànṣe Báǹkì Àgbáyé ni ó hàn nínú ètò ìṣúná gẹ́gẹ́ bí àpápọ̀ owó tó wọlé ní ọdún náà, iye owó tó dín ní Bílíọ̀nù Mẹ̀rìnlélógún Náírà (₦23,840,933,058.00) ni wọ́n lérò pé ó jẹ́ owó tí a yá láti owóyàá àgbáyé ṣùgbọ́n iye owó àkànṣe iṣẹ́ tí wọ́n fi ẹ̀yawó nàà ṣe kò jẹyọ nínú ètò ìṣúná

- Ó yẹ kí ìlànà tó tọ́nà wà nípa pínpín owó nàà lórí iṣé àkànṣe àgbáyé sí ìsọ̀rí owó-ìná

## 10.00 PÍNPÍN ÌDÁMẸ́WÀÁ OWÓ TÓ WỌLÉ LÁBẸ́LÉ SÍ ÀWỌN ÌJỌBA ÌBÍLẸ̀

- Ẹ̀tọ́ Ìjọba Ìbílẹ̀ ní ìdámẹ́wàá owó tó wọlé lábẹ́lè sí àpò Ìjọba Ìpínlẹ̀. Nì ọdún tí a ń gbé yéwò yíì iye owó tó lé ní Bílíọ́nù Mẹ́wàá àbọ̀ Náírà (₦10,557,553,944.73) ló wọlé lábẹ́lé sí àpò Ìjọba Ìpínlẹ̀ gẹ́gẹ́ bí àkọ́ọ́lé ètò ìnáwó láti Ilé- iṣẹ́ tó ń ṣétò ìnáwó Ìpínlẹ̀ (Acountant General) gbé jáde. Ìdámẹ́wàá owó yíi tó yẹ kó lọ sí àpò Ìjọba Ìbílẹ̀ lé ní Bílíọ̀nù kan Náírà (₦1,055,755,394.47), Pẹ̀lú gbogbo àsọyé wa nínú àkọọ́lé wa ti tẹ́lẹ̀ àti ìwé ìṣèwádì tí nọ́ḿbà rẹ̀ jẹ́ AQ/SLIA/01/2019 tí a kọ sí ilé iṣẹ́ tó ń ṣètò ìnáwó Ìpínlẹ̀ (State Accountant General) lórí àìfún Ìjọba Ìbílẹ̀ ní ìdámẹ́wàá owó tó wọlé lábẹ́lè ní ọdún 2019.
- Kò sí àmì ìdánilójú pé wọ́n san ìdámẹ̀wá nàà sí àpò Ìjọba Ìbílẹ̀

## 11.00 OWÓ TÓ SỌNÙ

- Iye tó lé ní ọgọ́rùn-ún lé méje Mílíọ̀nù Náírà (107,384,799) tí ó sọnù ní àwọn Ilé-iṣẹ́ Ìjọba tí ọ́rọ̀ kàn ni wọn kò kọbi- ara sí, tí àwọn òṣìṣẹ́ tó ń ṣétò ìnáwó ni àwọn Ilé-iṣẹ́ Ìjọba náà kò tilẹ̀ gbé ìgbésẹ̀ láti ṣàwárí owó nàà.

## 12.00 ÀWỌN ÌDÓKÓWÒ ÌJỌBA

- Àwọn ìdókówò méjì tí àpapọ̀ iye rẹ̀ lé ní Bílíọ̀nù kan Náírà (₦1,255,244,342.00) tó wà lọ́dún tó kọjá lo ṣì wá ní ọdún tí a ń yẹ̀wò. A kò rí àrídájú rẹ̀ nínú àkọọlẹ̀ ìdókówò nínú ètò ìnáwó bóyá. Aládàání, Àjọsepọ̀ tàbí èyí tí wón ń ṣàkóso rẹ̀ ní àwọn ìdókówò náà. Ó ṣe pàtàkì kí a ní òye nǹkan wọ̀nyí nínú àkọọlé ètò ìnáwó tí ọjọ́ iwájú. Ó ṣe pàtàkì láti kíyèsí pé ìdókówò wọ̀nyí kó mú owó kànkan wọlé lọ́dún tí a ń gbé yẹ́wò yíì

- Ohun ìní ìdókówò nàà lórí ìwé dín díè ní Bílíọ̀nù Mẹ́tàlá Náírà (₦12,947,265,000.00) títí di ọjọ́ kọkàn lé lọ́gbòn oṣú kejílà ọdún 2020 lẹ́yìn áyọkúrò ọlọ́dọọdún tó lé ní Mílíọ̀nù Méje Náírà (719,292,500.00). Owó to wọlé láti ìdókówò nàà le ni Bílíọ̀nù kan Náírà (₦1,304,432,815.40) ní ọdún tó kọjá lọ sùgbọ́n tí kò mú owó kankan wọlé lọ́dún tí a ń gbé yẹ́wò. Bí owó kankan kò ṣe wọlé lórí ìdókówò Ìjọba tí iye rẹ̀ fẹ́rẹ̀é tó Bílíọ̀nù Mẹ́tàlá Náírà (₦12,947,265,000.00) jẹ́ kàyéèfì fún àwọn Ayẹ̀wé-owó-wò.

## 13.00 ÀTÚNYẸ́WÒ ÌṢÀKÓSO ÌṢÈTÒ ÌNÁWÓ

- Ó yẹ kí wọ́n ṣe àtúnyẹ́wò ìṣàkóso ètò ìnáwó Ìjọba tí wọ́n ń lò báyìì ní ìbámu pẹ̀lú ètò ìṣàkóso ètò ìnáwó tí wọ́n sẹ́sẹ̀ ṣe kí wọn sì ṣe àgbékalẹ̀ kòkáárí Ilé-iṣẹ́ Àyẹ̀wò-owó-wò tí abẹ́lé (Central Internal Audit)

- Àwọn ìwé ìṣàkóso Ètò Ìnáwó kò sí lórí àtẹ fún rírà yálà ní Ilé- iṣẹ́ Ìjọba tàbí Ilé- iṣẹ́ Ìkọ́ni fún àwọn òṣìṣẹ́ (Civil Service Commission or Office of Establishment and training).
- Kí ìwe ìṣàkóso Ètò Ìnáwó wà lórí ìkànnì Ìjọba Ìpínlẹ̀ Èkìtì fún ànfàání àwọn tó bá nílò rẹ̀.

## 14.00 ÈTÒ ÌṢÀKÓSO LÁBẸ́LÉ

- Ètò ìṣàkóso lábẹ́lé tó múnádóko kò tó pàápàá fún Ilé-iṣẹ́ Àyẹ̀wé-owó-wò lábẹ́lé

- Àkọ́ọ̀lẹ́ àyẹ̀wò olósoosù Àyẹ̀wò-owó-wò lábẹ́lé láti àwọn Ilé-iṣẹ́ Ìjọba kò wà ní ìbámu pẹ̀lú ohun tí a jíróró lé lórí tẹ́lẹ̀

- Àkọ́ọ̀lẹ́ tó kúnjú ìwọ̀n tó sì báramu ni ó gbọ̀dọ̀ jẹ́ àkọ́ọ̀lẹ́ àyẹ̀wò olóṣooṣù Àyẹ̀wò-owó-wò lábẹ́lé

## 14.00 ÀWỌN OHUN TÓ Ń FẸ́ ÀMÓJÚTÓ NÍ ILÉ-IṢẸ́ AYẸ̀WÉ-OWÓ-WÒ ÀGBÀ TI ÌPÍNLẸ̀ ÈKÌTÌ

- Òṣìṣẹ́ kò tó
- Ìdánilẹ̀kọ̀ọ́ àti ìdàgbàsokè àwọn òṣìṣẹ́
- Ètò ìnáwó
- Ọkọ̀ àfiṣiṣẹ́
- Ọ́fìisì fún àwọn òṣìṣẹ́ s

15/06/2022.

**Adeuya Victor Oluwole (ACarb, CFA, ACA)**
**Auditor-General,**
**Ekiti State**